**Lakaye Ọrọ**

Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbawẹ, fi ororo kun ori rẹ, ki o si bọju rẹ. Ki iwọ ki o maṣe farahan fun enia pe, iwọ ngbawẹ, bikoṣe fun Baba rẹ ti mbẹ ni ikọkọ: Baba rẹ ti o si riran ni ikọkọ yio san an fun ọ ni gbangba (Matteu 6: 14-18).

Irohin Yoruba

NO. 822. MARCH 8 — MARCH 14, 1961 KOBO MEJI (2D)



Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# AWỌN ARA AGBOR Ṣ'EYẸ FUN OLOYE AWOLỌWỌ





Aworan yi ni ti igbati awọn ara ilu Agbor nṣẹyẹ fun Oloye Awolọwọ ti Ọgbẹni D. O. Oare, si ngbe ida le e lọwọ. Nwọn tun fun Oloye Awolọwọ ni iwe ayẹsi ti ikini kuabọ pẹlu.

## Ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre uun AGBOR

***Ọjọ nla ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi jẹ fun gbogbo awọn ara ilu Agbor lọjọ na ni nwọn gba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria lalejo nla, ti nwọn si ṣe ẹyẹ fun un.***

Ọjọ na ẹwẹ ni ipade gbogbo-gboo Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti agbegbe Agbedemeji aala Ipinlẹ Iwọ-Orun (Action Group Mid-West Conference) bẹrẹ ni Agbor, Oloye Awolọwọ lo ṣe Alaga ipade na.

Aworan oke yi ni ti igbati Oloye Awolọwọ pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ na nfẹ wọ ile ipade. Dọkita S. O. Ighodaro, Minista Alamojuto Eto Idajọ Ododo ni Ipinlẹ Iwọ--Orun lo wa ni ọwọ osi, Oloye Anthony Enahoro lo wa ni ẹgbẹ ọtun.

## Balewa lọ si Londonu

OLỌLA Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria fi ilu Eko silẹ lọ si Londonu 'nu ọkọ ofurufu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi lati lọ ba wọn ṣe ipade awọn Alakoso Ijọba Agbaiye to faramọ Geesi (Commonwealth Prime Ministers' Conference).

Ipade na yio bẹrẹ loni, ọjọ 'Ru ti i ṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni Londọnu, o si jẹ akoko ipade ti ilu Naijiria yio ba wọn ṣe.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Oloye Adebọ ni iwa imẹlẹ ko tọ si ẹnikẹni

OGUNLỌGỌ awọn ọmo Ijọ "Anglican" ti nwọn ṣe ipade apejọ awọn Alufa ọdọdun ni Ibadan lo pesẹ laipẹ yi lati gbọ ọro iwuri ti Oloye S. O. Adebọ, Akọwe-agba Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ba wọn sọ nipa eto ilọsiwaju aje ni Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Oloye Adẹbọ sọ fun awọn enia tį wọn wa sibi ipade na pe bi a ba nfẹ ki ilu wa Naijiria ni ilọsiwaju nipa owo, iṣẹ ati gbogbo ohun ti ngmu alafia wa fun ilu, "gbogbo wa ni lati ṣe iṣẹ aṣekara, a ko si gbọdọ ṣe imẹlẹ". O ni on ti mgbọ ti awọn kan ti nsọ kiri pe eeṣe ti Ijọba ko ṣeṣe iwe owo ko pọ to eyiti yio fi to ẹnikẹni lọwọ fun nina, ti yio sį tun to fun Ijọba papa, dipo pe Ijọba yio ma a ni kį awọn ara ilu na san owo ori. Oloye Adebọ ṣe alaye pe bi awọn enia ba mọ nipa iwe owo-ṣiṣe ni, nwọn ko ni ro ero lọ sibi iru nkan bẹ ẹ.

O ni ede-aiyede ko ni lati sį nipa eyi bi enia ba mọ pe Ijọba ko le tẹ awọn iwe owo jọ jaburata lalai jẹ pe nwọn fi iṣiro si bi ọja ti nta si, ati bį owo paapa ti niọ deede si. Oloye Adebọ fi ye wọn pe bi Ijọba ba lọ ṣe gẹgẹbi awọn miran ti nro, igba kan yio wa de ti yio jẹ wipe iwe owo paapa ko ni wulo mọ fun awọn ara ilu ati fun Ijọba na. O wa tun fi ye wọn dada pe Ijọba ko le ṣe iwe owo rara, bikoṣe pe ki nwọn wa owo lọwọ awọn ara ilu lati fi tun ilu na ṣe.



OLOYE ADEBỌ

Oloye Adebọ sọ pe ohun ti Ijọba nfẹ ni anfani ilu, irọrun fun awọn ara ilu, atį idẹra fun gbogbo ẹnikẹni, ṣugbọn eyi ko le ṣe, bi o ba jẹ pe ọpọ owo ni yio ma a wa awọn enia diẹ ti ko jẹ pe awọn enia pupọ ni ngwa owo kiri.

Ni ipari ọrọ rẹ. Oloye Adebọ wa fi ẹnu ba ọrọ nipa rogbodiyan larin ilu. O ṣe ifilọ nipa rogbodiyan wọnyi ma nsaaba ṣẹlẹ bi awọn enia ba fẹ fi ibinu wọn han lori ohun ti Ijọba ba ṣe, yala nipa owo-ori sisan ni, tabi nkan miran ti Ijọba ba ri pe ẹtọ awọn ni lati ṣe si ilu.

O ni ki iṣe ewọ fun awọn ara ilu latį fi ibinu wọn tabi atako wọn han si nkan-ki-nkan ti Ijọba ba ṣe, o ni ki i si i ṣe Naijiria nikan ni nwọn nṣe iru nkanbẹ, o ni ṣugbọn bi awọn mọ nkan tį Ijọba ba ṣe, tabi ti nwọn ngbero lati gbe jade, o ni ki iṣe ọna ija, tabi ọna ijamba ni o yẹ kį awọn ara ilu ma a fi ibinu nwọn han. O ni yio dara pupọ bi nwọn ba le ma a ṣe atako wọn ni ọna ẹtọ ati iyi, eyiti yio ma a fi han awọn enia miran ni ilu okeere pe nitotọ, Naijiria ti to da duro fun ara rẹ, gẹgẹbi orilẹ ede.

Oloye Adebọ si ṣe alaye pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ko dẹkun igbiyanju fun ilọsiwaju ilu.

### Otutu fẹrẹ ti fun un ni "K.O.!"



1. Nigbati o ku ọjọ meji lati ja ija nla na—Battling Sam bẹresi wukọ o si esin.

2. Alabojuto rẹ ni: "Ọgbeni—a ni lati le otutu yen lọ ni" Ṣugbọn lọna wo? Lẹsẹkẹsẹ ni o ranti—Mentholatum.



3. Lẹhinti o fi Mentholatum atura ati adẹra pa ara l'akọkọ, Sam bẹrẹsi gbadun. Nigbati o ku wakati diẹ ki o de agbo ni eegun ija rẹ ti naro.

4. Ija nla na de, Battling Sam bẹ s'agbo bi amọtẹkun lati gbe onija rẹ ṣanlẹ lori ija karun. Gbogbo enia ho gee pe "Sam ọoku-toọ" Sam ni "opẹlọpẹ Mentholatum" "Dajudaju o gbọn otutu mi nu.

Fi Mentholatum bọ inu rẹ—ki o si ma a mi pẹlu irọun. Fi diẹ pa aiya rẹ—ki o si fọwọ ra a wọnu! ikọ rẹ yio lọ laipẹ. Mentholatum atura ati adẹra naiṣẹ bi idan ni nigbagbogbo! Menthoatum dara fun jẹdi-jẹdi, pẹlu —a tete mu itura wa! Ri i daju pe ojulowo Men-tho-lay-tum ti o wa ninu awọn ọangolo ati awọn idẹ gẹgbi awọn aperẹ won yi ti o bere fun. Maṣe ra awọn adamọdi.



Awọn nikan ti nwọn nṣe ni

**MENTHOLATUM CO. LTD**
(Est. 1889), Slough, England

**MENTHOLATUM**

IPARA TI O DARAJU



# Awolọwọ gbayi ni ilu Abak ati Agbor





NI ABAK

[illegible]

NI AGBOR

[illegible]



## Atoyebi bọ Olotu wa

[illegible]



[illegible]






## Ijọba f'aramọ awọn oloye Ibadan meji

IBADAN

[illegible]

## Shehu gba idajọ ẹwọn oṣu mẹsan

IBADAN

[illegible]

## AKIYESI PATAKI

[illegible]

OLOTU




# Classified Advertisements


AWỌN Atamatase oogun lorişirişi, iwe Egbogi Ajẹbidan Agbabiętu 25s.—SHOYINKA 6, Ojo Road,

AWỌN IWE KO ṢE MANI. Iwe egbogi fun oniruru iwosan, iwe adura Işẹgun awọn ajẹ; iwe Ifa Agbọn-niregun, iwe Itumọ Ala pẹlu iwadi nkan; iwe lilo ati agbara Psalmu; iwe Adura tete da mi lohun, iwe itan Abalaiye ati ti Işẹdalẹ. Kọwe fun iwe-itaja—OLOTU Box 104, Ebute Mẹtta, Nigeria.

AKIYESI PATAKI

UNITED Brethren Prayer Group "Ẹgbẹ Fẹ Ẹnikeji Rẹ gẹgẹbi ara rẹ"—Eyiti ọpọlọpọ enia mọ si "The White Brotherhood Lodge". Njẹ iwọ ha mọ ohun ti agbara adura jẹ bi? Tabi o ha ti gbọ nipa işẹ ribiribi ti Ẹgbẹ oke yi nşe fun ẹniti o ba wa ninu idamu, ti o wa ninu aiye bi ẹnipe ko si l'aiye. Lọrọkan, kọwe si Akọwe Ẹgbẹ oke yi fun Iwe Alaye pipe nipa Ẹgbẹ yi. SECRETARY, Box 64, Yaba, Nigeria.

FUN awọn iwe lilo ti o darajulọ fun Ile-işẹ, ki o wa wo wọn tabi ki o fonu si Ile-itaja IMỌTA Dual Trading Company ti işẹ "Eka The Stationery Association of Great Britain and Ireland" ni 14 Joseph Street, Lagos. Phone 23981. Awọn owo ọja wa fanimọra pupọ o si ni ẹdinwo dada lori iye ti o ba ra, a o si ba o ko o de ile rẹ lofẹ. Bi o ba wa ra ọja lẹkan, yio fa ọ mọra. A nfi apejuwe awọn ọja na (sample) ransẹ si awọn ti o ba bere.

ỌJA TITUN TI A RI GBA —Iwe Aşiri Ọba Solomon 20s., Iwe Aşiri Ọba Dafidi 20s., Iwe Kẹfa, Keje, Kẹjọ ati Kẹsan Mose 20s. Lilo ati agbara Psalm 5s. 6d., Iwe Ala 5s. 6d. Iwe Adura pẹlu Orukọ Mimọ Jehovah 5s. 6d., Iwe Adura Aşiri fun awọn Ẹgbẹ Aladura bi Ijọ Kerubu ati Serafu 5s. 6d., Iwe Iwosan awọn Adahunşe 2s., Iwe Ilana Pool lede Yoruba 2s. ati ogunlọgọ ohun miran. Kọwe si MANAGER: 15, Araoti Street, Yaba Nigeria.

1. General Knowledge jẹ iranlọwọ pataki lati ma mu awọn ọmọ ilewe pass gbogbo idanwo wọn. 2. General Intelligence jẹ Ijinlẹ Ẹkọ pataki fun awọn ọmọ ilewe. 3. English Yoruba kọ ni lede Oyinbo ju London lọ. 4. Iwe Owe Titun Akarẹrin wa fun faaji lasiko Igbẹyawo Ikọmọjade o si dẹrin pania lasiko ibanujẹ. 5. Iwe Aiye Ominira Akamọra kun fun ijinlẹ ọgbọn ati oye. 6. Iwe Aiye Akamọra li ede Oyinbo. 2s. 6d. Ẹyọkọkan latoke delẹ 6d. owo Iposu, 18s. dozen, 5s. owo Iposu. E fowo ransẹ si The MANAGER, Dalẹgan Trading Services, Box 48, Gegele Street, Ilọrin.

AWỌN IWE KOŞEMANI Iwe Egbogi Ajẹbidan Agbabiẹtu 25/- Iwe Ilana Ifa, Etutu-şişẹ, Iwosan ati Egbogi atamatase 25/- Turari Itaja ẹyọnu agba (Pangolo) 20/- Psalmu Işẹgun agba, aiye pẹlu turari adura 30/- Gbedegbẹyọ Hausa 3/- Iwe itumọ ala kikun 7/6d. Postage 1/- Manager, 6, Ojo Road, Oduabọrẹ Mushin.


# AKEDE IGBALA

(Lati oju ewe keje)

nwọn şe ki nwọn to le ri iwosan.

Ohun na si ni pe ki Mose ki o rọ ejo idẹ kan ti o si gbe e si ori ọpa rẹ, iye awọn ti o ba le gbe oju wọn soke ninu irora lati wo o, nwọn yio si ri igbala fun ẹmi wọn kuro ninu oro ejo na .Şugbọn ẹniti ko ba wo o ki yio ri iwosan bẹni yio si ku.

## IKU GBIGBONA

Bi Mose ti rọ ejo amubina na ti o si gbe e si ori ọpa, ọpọ awọn enia ni ko wo ori ọpa na ti nwọn ka a si ohun lasan ti nwọn ko si mọ pe ni ara ọpa na ni iye wọn wa, bẹni gbogbo wọn si ku. Iye awọn ti nwọn gbe oju soke lati wo ọpa na ri igbala ni ọjọ na nwọn si ye kuro ninu iku gbigbona ti ara ati ti ẹmi.

Nigbati Paulu nsọ fun awọn ara Kolose pe ki nwọn ma wo awọn nkan ti mbẹ loke, o nsọrọ nipa Jesu Kristi Oluwa ati onişegun nla na. Pe, bi nwọn ba le gbe oju wọn si ara Rẹ wọn yio ri iwosan fun ẹmi wọn.

"Ẹ ma ronu awọn nkan ti mbẹ loke ki işe awọn nkan ti mbẹ li aiye" (Kolosse 3: 2). Jesu Kristi na tun nrọ wa loni pe ki a ma a wo On nikan ki a wa ba le ri iye fun ọkan wa.

Iwọ na ti wo Jesu ẹniti a kan mọgi nitori ẹşẹ rẹ bi? Njẹ iwọ na ha ti mọ Ọ ni Oluwa ati Olugbala Rẹ? Bi iwọ ko bai ti mọ Ọ ti iwọ ko si ti gbe oju rẹ soke si ọdọ Rẹ, Akede Ọna Igbala ngba ọ niyanju loni lati şe bẹ, ki o le ri iye ainipẹkun ti mbẹ ninu Rẹ.

"Kọju si mi, ki a si gba nyin la, gbogbo opin aiye: nitori emi li Ọlọrun, ko si ẹlomiran" (Isaiah 45: 22). Jesu Kristi ko ha farahan ninu Ọlọrun bi, nigbati O wi pe, "Emi ati Baba mi jẹ ọkan, ẹnikẹni ti o ba si t iri Mi o ri Baba"? Sa sọra fi awọn işọro rẹ si apakan ki o si wo Jesu iwọ yio si ye.

Iwọ ọrẹ mi ti nka iwe yi, nigbagbogbo ni a ngbe orukọ na kọja lọdọ rẹ ti iwọ ko fi oju si i lati wo o. Şugbọn maşe jẹki Jesu tun kọja loni lati wo o ki o si gba orukọ Rẹ gbọ.

Bi a ti nsọ ọrọ na fun nyin bẹni Ọrọ Ọlọrun paapa tun şe ẹlẹri fun wa pe, "Ki a ma wo Jesu Olupilẹşẹ ati Alaşepe igbagbọ wa; ẹni, nitori ayọ ti a gbe ka iwaju rẹ, ti o farada agbelebu, laika itiju si, ti o si joko l'owọ ọtun itẹ Ọlọrun" (Heberu 12: 2).




# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Olotu, ẹ ku owurọ. Ẹ ku işẹ o. Şe alafia lẹwa ati gbogbo ara ile?

OLOTU—Ma a wolẹ, Alapara, alafia ni mo wa. Ko si nkankan. O ma to ọjọ mẹta, şe ko si nkan ti mi o ri ọ lati ọjọ yi? Tabi o tun pada lọ si Ghana ni.

ALAPARA—Bẹẹkọ o, nko re ibikan. O ti şe mi koi diẹ ni. Lati igbati mo ti kuro lọdọ nyin ni ara mi ko ti da.

OLOTU—Pẹlẹ o, nko mọ rara. Ko pẹ na ti mo tilẹ bere pe a ko ri ọ, a ko tilẹ gbọ firi rẹ rara. Şe ara si ti kọfẹ nisisiyi.

ALAPARA—Ẹ şeun, mo dupẹ. Mo ti ngbadun dada. Fun nkan bi ọjọ mẹrin ti mo wa ni idubulẹ, nko fi oju mi kan ita rara. Nko tilẹ mọ ohun ti nlọ larin osẹ na, şugbọn nisisiyi mo ti ri alafia, mo si dupẹ lọwọ Ọlọrun fun alafia na.

OLOTU—A dupẹ, Oluwa ko tubọ şe ẹkun alafia na. Ko si ohun to to alafia. Alafia ni a fi ngbadun aiye. Ọjọ bi melo ti o fi wa ni aisan ni iwọ na le fi mọ riri alafia ara. Koşe ma-ni ni orukọ rẹ. O di gbati enia ko ba si ni ki oluwarẹ to mọ bi o ti ri.

ALAPARA—Bẹni ọrọ na ri, Olotu, mo gba gbogbo nkan ti ẹ sọ. Ẹ ku agba Ọlọrun ma jẹki agba tan lori ilẹ.

OLOTU—O şeun, Alapara, joko dada, ki o si fun mi "l'abari" toku nipa irinajo rẹ lọ si ilu Ghana.

ALAPARA—Ibiti mo ba ọrọ mi de nigbati a 'wa ni teşọnnu ọlọpa ni Lomẹ, ti a si ri nkan ti o nşẹlẹ nibẹ. Olotu, bi mba ni ki ngma ba ọrọ bọ nipa ilu Lomẹ, ilẹ yio kun, ti nko si ni le sọ gbogbo nkan ti mo ri nibẹ tan.

Nigbati o to aseko ti ọkọ wa yio şi, gbogbo wa ti pesẹ sinu ọkọ, ni a ba şi, o di Ghana. A de Ghana ni owurọ ọjọ keji, eyi ni pe a de Ghana lati ọjọ kẹta ti a ti kuro nile.

OLOTU—Ki ẹ to de Ghana, şe ẹ ko ri idiwọ tabi idana kankan loju ọna? Nitori irọ ti a ngbọ nipa oju ọna Ghana ko kere. Şe ẹ ko ri nkankan to jọ pe ajeji wa ninu ewu o?

ALAPARA — Ẹşeun, Olotu Ọlọrun ko jẹ ki a ri ijamba kankan loju ọna. Ibiti a o ba ti ri idaduro diẹ ni ilu ti nwọn npe ni Aflao. A duro nibẹ, şugbọn a ko ri idiwọ pupọ. Igba ti a fi wa nibẹ fun wa ni anfani lati rin kiri ilu na diẹ.

Bi a ti de Ghana şa ni a ti mu işẹ wa şe. Fun gbogbo igba ti a si wa nibẹ, a ri aye lati rin gbogbo awọn adugbo ti a ti ngbọ orukọ wọn.

OLOTU—Adugbo melo lo wa ni Ghana? Bawo ni titi ilu na ti ri?

ALAPARA—Nko mọ iye adugbo to wa ni Ghana. Titi ilu na dara, o si fẹ dada. Şugbọn iba ibiti mo de ni mo mọ nko le sọ nipa ibomiran. Ọjọ keji ti mo de Ghana şa ni mo mọ bi ilu na tiri. Ibiti mọto wati nlọ si ilu ti a fẹ lọ şe nkan ni a lọ de ibikan



ALAPARA IBADAN

ti a ri awọn enia to bi ogun. Nwọn dabi awọn lebira oşişẹ Bode. Nwọn si duro lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ti ri mọto wa. Nwọn nwo wa bi a ti mbọ. Ẹnu si ya wọn bi a ti nşe nigbati nwọn da mọto wa duro, nitori şe awa ko mọ nkankan, a şe bi awọn ti nwọn kan nşişẹ oju ọna ni. Aşe ibiti a gbe wa jẹ ibiti ajeji ko gbọdọ tara de nitori ibiti nwọn nwa golu (wura) ati ohun işurẹ ilẹ oniyebiye ni ibẹ. Nigbati a bọ silẹ, awọn ọga wọn bere pe kini a wa de ibiti a wa? A si sọ fun wọn pe a nlọ si ibikan ni, ati pe a ko tilẹ mọ pe ibiti awa jẹ ilu ti ajeji ko gbọdọ de.

OLOTU—Şe nwọn ko da nyin ni sẹriya nla? Nitori ibiti o wi yi ni lati jẹ ibiti Ijọba Ghana ti şe leewo fun ẹnikẹni lati gba kọja.

ALAPARA—Olotu, Ọlọrun lo yọ wa. Nigbati nwọn sọ ede Ghana si wa, a ko dahun, nitoripe a ko gbọ. Ẹniti o gbọ ede wọn ni awa-mọto, ko si ba wọn sọ ede na. Dipo rẹ, nşe ni o nsọ ede Asaba ti Naijiria. Nigbati nwọn ri pe a ko gbọ ede wọn, ti a ko si fi oju han bi ẹniti o wa wa golu, ni nwọn ba yi ede wọn pada si ti Gẹẹsi. A wa na si ba wọn sọ. Nwọn bere kini a wa de ibiti a de yi, a si sọ fun wọn pe a nlọ si ibikan ni, şugbọn ọkọ wa şeri gba ọdọ wọn nitori ibẹ ni o ya ju si ibiti a nlọ. Nwọn ba dariji wa nigbati nwọn gbọ alaye wa. Şugbọn nwọn ko dariji wa lasan o, Olotu.

OLOTU—Kini nwọn şe fun nyin?

ALAPARA—Olotu, ẹ jọwọ ẹ jẹki a fo iyẹn. Ẹ jẹki a gbagbe rẹ. ngo ma ba nyin sọ iyoku nigbamiran.

OLOTU—ẹẹşe, Alapara, o ti şe ya kiakia bayi? Lọjọ wo ni mo ti ri ọ gbẹhin? Jọwọ tubọ sọ diẹ fun mi nipa awọn onibode nyin yi, mo fẹ gbọ nipa wọn si i.

ALAPARA—Ẹ şeun, Olotu, oju kan mi ni, şugbọn ngo sọ diẹ fun nyin nipa awọn enia ti a ba pade ninu igbo golu yi. Ẹnikẹni to ba fẹ mọ bi iya ti njẹ ajeji si, ki o wa si ibiti mo nwi fun nyin yi. Oju rẹ yio ri nkan. Fun bi wakati kan ti a fi wa ni iduro, oju wa ri nkan ti nwọn npe ni 'Mọ-mọ'. Şugbọn ni ikẹhin a tan ọran na, nwọn si kilọ fun wa gidigidi ki a ma gba ibiti a gba na pada wa mọ o. Olotu, ẹ jẹ ki nduro nihin. Ngo tun ma ri nyin pẹsẹ-pẹsẹ. O digba.

OLOTU—Alapara, o şeun o, ngo ma a şe ireti rẹ.




# Awọn ọmọ Ijẹbu ati awọn ọmọ Ẹgbẹ Oduduwa ṣe ẹyẹ fun Awujalẹ l'Eko

**IROHIN ko to afojuba ni ti ẹyẹ ati iyi ti Ọba Alaiyeluwa, Sikiru Adetọna, Ọgbagba Keji, Awujalẹ Ijẹbu Ode, gba ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi lọdọ gbogbo awọn ara ilu Eko. Ni ọjọ na ni Ọba Alaiyeluwa yi wa ṣe abẹwo ilu Eko, eyi si ni akọkọ wa rẹ lati igba ti o ti gun ori oye awọn Baba Nla rẹ.**

Awọn ọmọ Ijẹbu to wa l'Eko, Ebute Mẹtta, Yaba, Mushin, Oshodi titi de Ikẹja lo wa ṣe ẹyẹ nla yi fun Ọba wọn. Ero pọ lapọju, ti enia ba nwo ori kereni (Carter Bridge) lati Iddo titi de Idumọta, enia dabi omi. Pẹlu ijo ati ayọ ni nwọn si mba bọ wa.

Gbara ti Ọba Alaiyeluwa na ti de Idumọta, ni nwọn ti da mọto-ayọkẹlẹ rẹ duro, ti on na si bọ silẹ lọ sibi ere iranti awọn ti o ti ku si ogun, o si fi oso mariwo (wreath) lelẹ nibẹ fun iranti awọn to ti ba ogun lọ.

Bi o ti kuro nibẹ ti o si bọ sinu mọto-ayọkẹlẹ rẹ ni awọn enia tun bẹrẹsi ṣe ere, ti nwọn njo, ti nwọn si yọ, nwọn si ko ẹyẹ na titi de Onikan ni gbalansa "King George V Memorial Park.

Nibẹ ni awọn ọmọ Ijẹbu ati awọn ọmọ Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa gbe wa ṣe ẹyẹ nla fun un. Nwọn fun ni iwe ikini-kuabọ, nwọn si tun fun un ni ẹbun oniyebiye pẹlu. Ninu iwe ikini-kuabọ yi, nwọn ni inu awọn dun lati ri Ọba na l'Eko, nwọn si ṣe adura pe ki Ọlọrun O fun un ni ẹmi gigun lo, ki igba rẹ si dara fun gbogbo ilu

### IFẸ ATI AYỌ

Ninu esi rẹ, Ọba Alaiyeluwa yi dupẹ gidigidi lọwọ gbogbo awọn ti nwọn ṣe ẹyẹ fun un, ati ti ẹbun nla ti nwọn fi ta on lọrẹ. O ni ifẹ ati ayọ ti nwọn fi gba on yi jẹ ohun iwuri fun on pupọ, o si gba wọn nimọran pe ki nwọn ma ṣe jẹ ki irẹpọ na ja. Ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ijẹbu lo pe sibi aṣeyẹ na.

Ni ọjọ keji, iyẹn ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi, Ọba Alaiyeluwa na ṣe Alaga nibi ere alarinrin ti awọn ẹgbẹ elere idaraya ti orukọ rẹ (njẹ "AAA of Nigeria" ṣe ni gbalansa ọdan "National Stadium" ni Surulere.

Ọba Alaiyeluwa na pada si Afin rẹ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi. Ki Ade o pẹ lori, ki bata o pẹ lẹsẹ Ọba o.



ỌBA ALAIYELUWA SIKIRU ADETỌNA


## ANFANI IṢOWO ATI IṢẸ-ỌWỌ

Jẹki owo tubọ ma a wọle fun ọ si i ki o si ṣe alekun owo-oṣu rẹ, ere lori iṣẹ-agbaṣe ati ere owo ọdun ti o nwọle taara nipa riranṣẹ ọja lati oke okun, fifi ọja ranṣẹ si oke-okun ati rira ọja larin ilu fun tita. Gbogbo oniruru ẹya aṣọ, awọn aṣọ alarabara ati olowu, Egbogi oriṣiriṣi, awọn ohun ikọwe, awọn ọja onirin, awọn ọja onjẹ, awọn ọja owu ati aṣọ, awọn adamọdi ọja iyebiye, awọn ohun-iṣire ọmọde, awọn ọja eso-igi ati ti ohun ọgbin ati awọn ohun-eelo onjẹ ati bẹ ẹ bẹ ẹ lọ titi.



Joko sinu ile rẹ, awọn ọja ti o nranse fun nigbagbogbo yio si ba ọ. Kọwe ki o si fi SITAMPU sinu apo iwe fun ibere awọn nkan ti o nfẹ, iye owo ọja ati eto adehun owo si: THE MANAGER,

**SEGUN COMMERCIAL STORES**

P.M.B. 2077, G.P.O. LAGOS

N.B.—Awọn ti o ba kọwe lati dalẹ kọja Naijiria nilati fi Postal Order oni ṣile kan (1s.) ranṣẹ lati tete da esi pada pẹlu ọkọ-ofurufu.





Published by Allied newspapers Limited. Elephant House 214 Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited, 5/7, Apongbon Street, Lagos. Fun owo 'IROHIN YORUBA' odun kan EKO sile mejo ati kobo mejo (8/8d). Ilu miran ni Nigeria ati Oke-Okun sile metala (13s) Olotu S. M. Ademuyiwa 2, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.